# Àyẹ̀wò Ogun Ẹnu Nínú Àṣàyàn Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá

**Prof. Olúyẹ́misí Adébọ̀wálé**
*Yemisi_adebowale@yahoo.co.uk*
*and*
**Tèmítọ́pẹ́ Olúmúyìwá, *Ph.D.***
*oluolumuyiwa@gmail.com*
*and*
**Jùmọ̀kẹ́ Aṣíwájú**
*jumokeayaasiwaju@gmail.com*
*Department of Linguistics and Languages*
*Adekunle Ajasin University*
*Akungba-Akoko, Ondo State*

## Àṣamọ̀

*Oríṣi ogun méjì tí ó lè dojú kọ ẹ̀dá nílé ayé ni ogun rírí àti ogun àìrí. Ọ̀kan lára ogun àìrí tí ó lè ja ènìyàn ni ogun ẹnu. Ogun ẹnu kì í ṣe ogun tí a ń fi nǹkan ìjà olóró bí ìbọn, ọ̀kọ̀, ọfà tàbí àdá jà. Kí wá ni a fi ń jà á? Báwo ni a sì ṣe ń jà á? Akitiyan àtiwá ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè wọ̀nyí wà lára ohun tó gún wa ní kẹ́ṣẹ́ láti ṣe àyẹ̀wò ogun ẹnu nínú àṣàyàn fíìmù àgbéléwò Yorùbá méjìdínlógún. A kọ́kọ́ ṣe àmúlò èrò Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹyọ nínú òwe láti sọ ohun tí ogun ẹnu jẹ́. Bákan náà ni a ṣàlàyé pé àwọn ohun tí ó lè ṣe okùnfà ogun ẹnu láwùjọ Yorùbá tí a gbé àwọn àṣàyàn fíìmù tí a yẹ̀wò lé ni ìlara, ìrẹ́jẹ, ipò àti yíyẹ àdéhùn. Àwọn nǹkan tí a fi ń ja ogun*

*ẹnu tí iṣẹ́ yìí mẹ́nubà ni èpè, ọfọ̀, orin àti èébú. Oríṣiríṣi ohun tí ó lè fa kí ogun ẹnu ja ẹ̀dá tí ó hànde nínú àṣàyàn fíìmù tí a ṣe àyẹ̀wò ni a fi kásẹ̀ àlàyé wa nílẹ̀.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** ogun ẹnu, fíìmù àgbéléwò, èpè, ọfọ̀.

## Ìfáárà

Àwọn onímọ̀ lóríṣiríṣi ni wọ́n ti sọ̀rọ̀ lórí ogun jíjà ní ilẹ̀ Yorùbá. Lára àwọn onímọ̀ bẹ́ẹ̀ ni Johnson (1921), Adéoyè (1979), Adéníji (1987), Ìbítóyè (2012) àti Sàlámì àti Ọláwálé (2013). Nínú àwọn onímọ̀ wọ̀nyí, Adéoyè (1979) àti Adéníji (1987) nìkan ni wọ́n ṣàlàyé kíkún lórí ohun tí ó lè fa ogun. Wọ́n mẹ́nuba òfin, ìpalẹ̀mọ́, ohun èlò ìjagun àti ọ̀nà tí àwọn ará ijọ́un ń gbà jagun nílẹ̀ Yorùbá. Àwọn onímọ̀ yòókù kan mẹ́nuba apá kan nínú àwọn ogun tí wọ́n ti jà nílẹ̀ Yorùbá ní ọ̀rúndún kọkàndínlógún ni.

Adéoyè (1979:295) ní oríṣi ogun méjì ni ó wà. Èkíní ni ogun àdájà, ìyẹn ni ogun tó dójú kọ ẹnìkan bí òfò alẹ́, ọ̀ràn, àrùn àti oríṣiríṣi ìdánwò. Ìkejì ni ogun àjàkúakátá níbi tí aáwọ̀ ti máa ń fa kí alágbára méjì tàbí ìlú kan dìde ogun sí ìkejì. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èrò Adéoyè (1979) yìí jẹ́ òótọ́ dé àyè kan, oríṣi ogun méjì tí àwa gbà pé ó wà ni ogun rírí àti ogun àìrí. Ìdí ni pé àwọn agbára àìrí kan wà tí àwọn tí ó ń ja ogun àjàkúakátá (iyẹn ogun rírí) máa ń bẹ̀ lọ́wẹ̀ ṣáájú kí wọ́n tó lè ṣẹ́gun. Lára àwọn agbára bẹ́ẹ̀ ni ìrúbọ sí àwọn òrìṣà, òǹnilẹ̀, àjẹ́ ati bẹ́ẹ̀ lọ. A kò sì lè sọ pé ti àwọn agbára àìrí wọ̀nyí

'báwo?'. Àwọn agbára àìrí wọ̀nyí náà ni ó ń kojú ẹni tí ó ń ja ogun àdájà. Nítorí náà ni Yorùbá fi máa ń sọ pé 'kí ọba òkè gbà wá lọ́wọ́ ogun rírí àti ogun àìrí' Wọ́n tilẹ̀ tún máa ń sọ pé 'kí ọba òkè bá wa ṣẹ́ ogun rírí àti ogun àìrí.' Ogun ayé kì í ṣe ohun tí a máa fi àdá, ọ̀kọ̀ àti ibọ̀n jà nikan. Nígbà mìíràn, ẹnu ni a máa lò. Bóyá èyí ni Yorùbá rò tí wọ́n fi máa ń pe ènìyàn ní *Apanimáyọdà*. Ìyẹn nìkan kọ́, Lára oríkì Àkúrẹ́, olúìlú ìpínlẹ̀ Oǹdó ni *Àkúrẹ́ lọmọ amúdàsílẹ̀ fi ogun ẹnu pa ni*. Èyí ló ṣe okùnfà ṣíṣe àyẹ̀wò ogun ẹnu nínú àwọn àṣàyàn fíìmù àgbéléwò nínú pépà yìí. Bí ó bá yẹ̀ ní Adétóyè (2009, 2015) nìkan, a kò rí àkọsílẹ̀ mìíràn mọ́ lórí ogun ẹnu láwùjọ Yorùbá. Iṣẹ́ wa yàtọ̀ sí ti Adétóyè (2009, 2015) tí ó gbé lé àṣàyàn iṣẹ́ àpilẹ̀kọ lítíréṣọ̀ Yorùbá kan. Inú àṣàyàn àwọn fíìmù àgbéléwo Yorùbá tí a gbé iṣẹ́ yìí kà yóò jẹ́ kí a rí oríṣiríṣi ọ̀nà bí àwọn Yorùbá ṣe ń fi ẹnu ja ogun. Bákan ni yóò tan ìmọ́lẹ̀ sí bí ogun ẹnu ṣe ń ja ẹ̀dá. A ṣe àmúlò fíìmù àgbéléwò Yorùbá nítorí pé ó jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà tí a fi ń mọ bí àwùjọ ti rí, Mgbejume (2006: 36). Ohun tí ó hàn gbangba ni pé fíìmù ṣíṣe ti gbàyà lọ́wọ́ ìwé lítíréṣọ̀ kíkọ àti títẹ̀ jáde lédè Yorùbá lónìí, bẹ́ẹ̀ owó tí a fi ṣe fíìmù kan jáde wọ́n ju owó tí a fi n tẹ ìwé jáde nígbà mìíràn. Bí fíìmù mẹ́wàá bá jáde lọ́sẹ̀, ìwé aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ méjì lè má jáde lọ́dún. Ìyẹn ọ̀kan. Ìkejì ni pé a kò nílò mọ̀ọ́kọ-mọ̀ọ́kà kí a tó wo fíìmù tàbí mọ ohun tí ó dálé. Bẹ́ẹ̀ ẹni tí kò bá mọ̀wèé kà kò ní lè ka ìwé lítíréṣọ̀ kó fa kòmóòkun rẹ̀ yọ.

Àwọn fíìmù àgbéléwò tí a gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí ni *Ààrẹ Apàṣẹ (2012), Àbẹ̀ní Alágbo-òru (2012), Àfọ̀njá (2001), Alákadá (2009), Bánkárere (2012), Báṣọrun Gáà (2003), Bùgá (2013), Èpè Ọjọ́sí (2013), Fọ́pomọ́yọ̀ (knd), Ibú (2012), Jẹ́jẹ́lóyẹ (2012), Kújẹ́nra (2012), Nimí (2016), Ogun Àgbẹ́kọ̀yà (2012), Ògbórí Ẹlẹ́mẹ̀ṣọ́ (knd), Pélé Mọ̀dínà (2013), Ṣijuwade (2017), Ti Olúwa ni ilẹ̀ (1995)* àti *Túlétúlé (2017).* Ohun tí ó mú wa yan àwọn fíìmù náà láàyò fún iṣẹ́ yìí ni pé ìlò tí wọ́n lo ẹnu nínú wọn jẹ mọ́ akòrí kókó ọ̀rọ̀ tí iṣẹ́ yìí dálé.

**Kí ni Ogun Ẹnu?**

Adétóyè (2009:20) sọ pé ogun ẹnu kún fún oníruurú ṣùtá tí a lè fi ẹnu ṣe, tí a sì sábà máa ń sọ síta pẹ̀lú ète àtigba ara ẹni sílẹ̀. Bákan náà ni Adétóyè (2015:413) ṣàlàyé pé ìlò agbára àìrí àti ọ̀rọ̀ líle la lè fi ja ogun ẹnu láti jẹ́ kí ohun tí a fẹ́ ṣe é ṣe ní kíákíá. Àlàyé méjèèjì tí Adétóyè ṣe fún ogun ẹnu dára dé àyè kan ni, kò fi gbogbo ara kógojá. Ìdí rẹ̀ ni pé ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ogun ẹnu lè má ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ìlò ọ̀rọ̀ líle gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó tọ́ka sí nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Bẹ́ẹ̀ ni ogun ẹnu tún lè má ní nǹkan ṣe pẹ̀lú gbígba ẹni sílẹ̀ rárá bí ó ṣe hàn nínú ìgbìyànjú Ìtawuyì nínú ìwé Akínwùmí Ìsọ̀lá náà. Lọ́rọ̀ kan, ogun ẹnu gbòòrò ju àlàyé tí Adéoyè ṣe.

Ní èrò tiwa, ogun ẹnu ni ìjà ahọ́n. Ìjà ahọ́n níí ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tí ẹnìkan sọ nígbà ìjà, tàbí tí ó sọ láti fi ẹ̀hónú hàn. Ó sì lè jẹ́ èyí tí ẹnìkan sọ láti gbèjà tàbí fi dáàbò bo ara rẹ̀ lọ́wọ́ ọ̀rọ̀

tí wọ́n sọ sí i láti fi bá a jà. Ní èrò àwọn Yorùbá tí àwa náà sì faramọ́, ìjà ahọ́n níí ṣe pẹ̀lú sísọ̀rọ̀ òdì sí ara ẹni tàbí ẹlòmíràn. Ìjà ahọ́n tún lè jẹ́ ọ̀rọ̀ asọjù, àìmọ̀rọ̀-gbé-kalẹ̀ àti àròká Nítorí náà ni Yorùbá fi n pa òwe[1] wọ̀nyí láti fi ìdí èrò wọn múlẹ̀.

i. Agúnbàjẹ́ kò lódo, ẹnu lodó wọn.
ii. Ẹnu àìmẹ́nu, ètè àìmétè níí kó wàhálà bá ẹ̀rẹ̀kẹ́.
iii. Ojú ni àgbà ń yá, àgbà kì í yá ẹnu.
iv. Gbogbo ohun tí ojú rí kọ́ ni ẹnu ń sọ.
v. Asọ̀rọ̀kẹ́lẹ́ bojú wògbẹ́, ìgbẹ́ kì í sọ̀rọ̀, ẹni à ń bá wí níí roni kiri.
vi. Ẹnu ẹ̀gà níí pẹ̀gà, ẹnu òrófó níí pòrófó, òrófó bímọ méjì, ó ní ilé òun kún fọ́fọ́.
vii. 'Àwá yó' fi ara rẹ̀ gbodì.
viii. Àìsọ̀rọ̀ìyánrọ̀ ló pa Elénpe ìṣáájú….
ix. Adásinilọ́rùn ìyàwó Ọ̀dọ̀gọ. Aládìyẹ́ ń wá adìyẹ rẹ̀, ó 'ní kí wọ́n jẹ́ kọ́kọ òun dé.
x. Ẹnu aláìsàn ní fi pe ikú. Ó ní 'Ǹjẹ́ àìsàn yìí kọ́ ni yóò pa òun báyìí?
xi. Ẹnu ni ìfà wà, ẹnu ara ẹni la fi kọ mẹ́ jẹ.
xii. Ẹnu ni adìyẹ fi ń ko ẹyin rẹ̀ jọ.
xiii. Bí a bá dákẹ́, tara ẹni a bá ni dákẹ́.

Ohun tí a rí fàyọ nínú àwọn òwe òkè yìí ni pé ènìyàn gbọ́dọ̀ kíyèsí ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀. Ọ̀rọ̀ tí ó ń bẹ nínú nìkan ni ènìyàn lè jọba lé, èyí tí a sọ jáde lè jọba lé ni lórí. Ìdí ni pé agbára tó wà nínú ahọ́n/ọ̀rọ̀ mú ju abẹ olójú méjì lọ. Àwọn tó bá sì mọ

ahọ́n wọn lílò láti bú ènìyàn ni Yorùbá máa ń pè ní Ẹlẹ́nu mímú/Eyínmujuabẹlọ. Àwọn ẹsẹ Bíbélì mélòó kan tilẹ̀ sọ pé iná ni ahọ́n. Ìwé Jóòbù 5:21 ní "A ó pa ọ mọ́ kúrò lọ́wọ́ iná ahọ́n". Ìwé Jákọ̀ọ̀bù 3:3-8 ní ohun burúkú aláìgbọ́ràn tí ó kún fún oró ikú tí ó ń pani tí a kò lè tù lójú ni ahọ́n. Láti fi hàn pé ọ̀kan ni ahọ́n àti ẹnu, Ìwé òwe 18:6 ní "Ètè aṣiwèrè bọ́ sínú ìjà, ẹnu rẹ̀ á pe iná wá." Ẹsẹ ifá kan nínú Odù Ọ̀wọ́nrín méjì fi yé wa pé ẹnu aráyé lẹbọ. Ó ní:

Ẹnu níí jẹ́ Olúbọ̀bọ̀ntiribọ̀, baba ẹbọ
Ǹjẹ́ kí ni wọ́n bọ ní Ifẹ̀
Ẹnu wọn, Ẹnu wọn là ń bọ nífẹ̀…
Ẹnu wọn… Abímbọ́lá (1977:xxiv-xxv)

Nítorí náà, iná ni ahọ́n, ọ̀rọ̀ tí ó sì ń ti ẹnu jáde lágbára. Àkíyèsí tí a ṣe fi hàn pé ènìyàn lè lo agbára ọ̀rọ̀ láti tẹ ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ rì tàbí hú ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ jáde ju bí wọ́n ti sọ lọ. Amy Neftzeger sọ ọ́ di mímọ̀ nínú http://www.goodreads.com/quotes/tag/words-of-wisdom pé: 'Sometimes the most appropriate response to an attack is not to engage, especially in situations where your own word may be used as weapons against you.' 'Lọ́pọ̀ ìgbà ni ó sàn kí a dákẹ́ ju kí a fèsì sí ọ̀rọ̀ tó lè fa ìjà, pàápàá níbi tí wọ́n ti lè fi ọ̀rọ̀ ẹnu mú wa.'

Àfàyọ tí a rí ṣe nínú ọ̀rọ̀ Amy Neftzeger yìí ni pé èsì tí ènìyàn gbọ́dọ̀ fọ̀ sí ọ̀rọ̀ kan kò yẹ kó tapo sí ọ̀rọ̀ tó wà nílẹ̀. Ṣé Yorùbá bọ̀, wọ́n ní 'gbólóhùn kan ba ọ̀rọ̀ jẹ́, gbólóhùn kan tún ọ̀rọ̀ ṣe. Àdúrà tí ọ̀pọ̀ ènìyàn ń gbà ni pé kí ayé má ti ibi

ọ̀rọ̀ mú wọn. Ìdí rè é tí Yorùbá fi ń sọ pé 'ọ̀rọ̀ tútù níí yọ obì lápò, ọ̀rọ̀ burúkú níí yọ ọfà nínú apó.'

## Ogun Ẹnu Nínú Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá

Àwọn onímọ̀ bí Jeyifo (1984), Adélékè (1995), Timothy-Asobele (2003:1) àti Àlàmú (2010:24) ti ṣe onírúurú àlàyé lórí ìbẹ̀rẹ̀ àti ìdàgbàsókè fíìmù Yorùbá. Àríyànjiyàn wà lórí fíìmù àgbéléwò àkọ́kọ́ lédè Yorùbá. Èrò Àlàmú (2010:28) ni pé *Igi dá* tí Kọ́lá Ọlátúndé gbé jáde ní ọdún 1990 ni fíìmù àgbéléwò àkọ́kọ́ lédè Yorùbá. Ṣùgbọ́n ìwádìí tí a ṣe lẹ́nu lọ́ọ̀lọ́ọ́ yìí àti akọ́ọ̀lẹ̀ tí a rí fi han pé Muyideen Arómirẹ́ (1961-2008) ni ó kọ́kọ́ gbé fíìmù àgbéléwò akọ́kọ́ lédè Yorùbá, ìyẹn *Ẹkùn,* jáde ní ọdún 1987 (Husseini, 2010:3). Lẹ́yìn náà ni Yẹkinni Oyèdélé gbé fíìmù *Ìlara* jáde ní ọdún 1990, (Husseini, 2010:6). Lọ́rọ̀ kan kì í ṣe fíìmù àgbéléwò Yorùbá kan ni ó jáde ní ọdún 1990 gẹgẹ́ bí Alàmú (2010) ti fẹ́ ká gbàgbọ́. Ọ̀kẹ́ àìmoye ni fíìmù àgbéléwò Yorùbá tí ó wà lórí àtẹ lónìí. Oríṣiríṣi kókó ọ̀rọ̀ ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọ́n sì dá lé lórí.

Nínú ìpín yìí, a ṣe àyẹ̀wò okùnfà àti ìlò ohun ìjà tí a fi ń ja ogun ẹnu. Ọ̀nà méjì tí a pín fíìmù àgbéléwò Yorùbá sí fún àyẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí ni: fíìmù ajẹmọ́-ẹ̀píìkì àti fíìmù àìjẹmọ́-ẹ̀píìkì. Àwọn fíìmù àgbéléwò ajẹmọ́-ẹ̀píìkì níí ṣe pẹ̀lú ìtàn/ìṣẹ̀lẹ̀ ìgbà ìwáṣẹ̀/àtijọ́. Abúlé ni ó sábà máa ń jẹ́ ibùdó ìtàn ẹ̀yà fíìmù yìí. Àwọn ohun èlò tí ó jẹ mọ́ ti ìbílẹ̀ Yorùbá ni àwọn máa ń mú lò. Ẹ̀ka-èdè Yorùbá pọ́nbélé ni wọ́n sábà máa ń mú lò. Lára fíìmù àgbéléwò bẹ́ẹ̀ tí a yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí

ni *Àfọ̀njá, Fọ́pomọ́yọ̀, Baṣọ̀run Gáà, Ògbórí Ẹlẹ́mẹ̀ṣọ́, Àbẹ̀ní Alágbo-òru* àti *Ààrẹ Apàṣẹ*. Ní idàkejì ẹ̀wẹ̀, àwọn fíìmù àgbéléwò àìjẹmọ́-ẹ̀píìkì máa ń dá lórí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwujọ òde òní. Àwọn èlò ìgbàlódé, èdè Yorùbá alábùla-èdè Gẹ̀ẹ́sì àti àwọn ibùdó ìtàn tó bá ìgbà mu ni wọ́n máa ń mú lò. Ẹ̀yà fíìmù yìí pé orísìrísìi. Ó lè jẹ́ mọ́ àwàdà, ẹ̀sìn, ọ̀daràn, ìfẹ́ àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Kò sí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ẹ̀yà fíìmù méjèèjì tí a mẹ́nu bà tí kò ṣe àfihàn ogun ẹnu láwùjọ Yorùbá.

Ọ̀pọ̀ nínú àwọn fíìmù àgbéléwò ajẹmọ́-ẹ̀píìkì ni wọ́n ṣe àfihàn bí a ṣe ń jagun nílẹ̀ Yorùbá àtijọ́. Nínú àwọn fíìmù náà ni a ti rí i pé àwọn alágbára kan wà ní àtijọ́ tí àwọn ohun ìjà olóró bí i àdá, ọ̀kọ̀, àti ìbọn kò ràn. Bóyá nítorí àjẹsára ni, a ò lè sọ. Bí wọ́n bá sì fẹ́ ṣẹ́gun wọn tàbí bí wọ́n bá fẹ́ ṣẹ́gun ọ̀tá, ohùn ẹnu ni wọ́n máa ń lò. Lára àwọn ohùn ẹnu bẹ́ẹ̀ ni ọfọ̀, àyájọ́, àṣẹ àti èpè. Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ bí Fábùnmi (1972), Ọlátúnjí (1984:139-168), Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2010), Olúmúyìwá (2016), àti Olúmúyìwá àti Aládésanmí (2017) ti ṣe àlàyé lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan ohùn ẹnu wọ̀nyí. Àwọn ohùn ẹnu náà ni wọ́n lè lò láti pa ni tàbí fi gba ara ẹni sílẹ̀. Nínú àwọn ohùn ẹnu wọ̀nyí, èpè nìkan ni kì í ṣiṣẹ́ lójú ẹsẹ̀. Wàràwàrà ni ọfọ̀/àyájọ́ ń ṣiṣẹ́. Ìdí ni pé wọ́n jẹ́ àkójọpọ̀ ìjìnlẹ̀ agbára ohùn ẹnu/ọ̀rọ̀ tí a rán níṣẹ́ láti mú kí ìrètí ohun tí a fẹ́ ṣẹ ní kíákíá.

Nínú fíìmù *Ààrẹ Apàṣẹ*, ọfọ̀ ni Aarẹ lò láti ṣẹ́gun àwọn ọmọ ogun ọ̀tá tí ó dojú ìjà ìbọn kọ àwọn ọmọ ogun tirẹ̀. O ní:

Àràǹkáyé loòrùn ń ràn.
Eeṣi kì í mọ ni kó tó fọwọ́ ba ni.

Èyí tí èwí ayé wí lẹ̀gbà ọ̀run ń gbà… Ilẹ̀! Ilẹ̀!!

Ẹ̀ẹ̀kan náà ni àwọn ọmọ ogun ọ̀tá bí i mẹ́ẹ̀dógún ṣubú lulẹ̀, wọ́n kú. Nínú fìímù yìí kan náà ni a ti rí Ààrẹ tí ó fi ahọ́n ba ètè kí ó tó pàṣẹ fún Adégúnwà tí ó ń gbo lẹnu nílùú kí ó má lè fọhùn mọ́. Ẹnu yìí kan náà ni Ààrẹ fi pọfọ̀ lé Adéróunmú tí ọba jíjẹ tọ́ sí kúrò nílùú nítorí ẹnu rẹ̀ gbọ̀rọ̀ jù. Níbi tí Ààrẹ̀ yìí gbádùn lílo ohùn ẹnu dé, ó máa ń dáṣà pé 'èmi la sọ̀rọ̀ ṣẹ tí kì í sọ̀rọ̀ dànù.' Ọ̀rọ̀ ẹnu ni wọ́n fi mú òun náà ní ìgbẹ̀yìn nítorí kò sí oògùn tí ó ràn án. Babaláwo ní tí wọ́n bá fẹ́ mu, kí wọ́n sọ̀rọ̀ tí ó lè bí i nínú. Ọ̀rọ̀ yìí ló gbọ́, tó ṣìṣe tó fi bínú pa ara rẹ̀. Ọfọ̀ yìí kan náà ni Fádèyí fi gba ara rẹ̀ sílẹ̀ lọ́wọ́ Àwòrò nígbà tí ó ń lépa rẹ̀ nínú fíìmù *Fọ́pomọ́yọ̀*. Ó ní:

> Olúpè mo pè.
> Olúpè mo pè
> Aṣọ́dẹ, Aṣọ̀dẹ
> Aṣọ́dẹ ló bí ilẹ̀
> Ilẹ̀ ló bí Aràrá
> Agómisanra ló bí Àrọ̀gìdìgbà
> Arọ̀gìdìgbà ló bí èmi Fádèyí
> Babaláwo tó bá ní oògùn lòun ó sà pa mí
> Àpabẹ́ ni tejò ọká,
> Oníṣègùn tó bá ní òun ó sà pa mí,
> Àpalàdọ̀ ni tejò erè,
> Àyípadà! Àyípadà!!

Báyìí ni Fádèyí Olóró ṣe yípadà sí ọ̀gà. Ó rá pálá wọgbó. Bákan náà nínú fíìmù *Ogun Àgbẹ́kọ̀yà,* ọfọ̀ ni Adékankẹ olórí àwọn obìnrin ìlú fi réyìn Ìrókò olórí àwọn ọlọ́pàá agbowó-orí. Ó ní:

Ẹfun níí bàwọ̀ osùn jẹ́
Osùn níí bàwọ̀ Ẹfun jẹ́
Àtẹfun àtosùn, eérú níí bàwọ̀ wọn jẹ́
Tiẹ bàjẹ́ lónìí o
Ẹ̀mú kan kì í múrin í tì lágbẹ̀dẹ
Gbogbo ibikíbi tí Ìrókò bá dé,
Ibẹ̀ ni kó dúró sí!

Ibi tí ọ̀fọ̀ náà ti bá Ìrókò ni ó gan mọ́. Ibẹ̀ ni àwọn obìnrin ìlú pá sí. Bákan náà ẹ̀wẹ̀, ọfọ̀ ni Ṣọ̀ún Ogunlọlá fi wá Ẹlẹ́mọ̀ṣọ̀ rí. Ó ní:

Dúdúdú níí jọba nílẹ̀ Mọ̀dudu
Mọ̀rẹ̀rẹ̀ níí jọba nílẹ̀ Mọ̀rẹ̀rẹ̀
A kì í fi dúdú bawo lójú
Kí dúdú lọ, kí ìmọ́lẹ̀ ó dé
Ẹlẹ́mọ̀ṣọ̀, mo ní kí n rí ọ…
Ìwọ nìyí, kásẹ̀ rẹ ńlẹ̀, mo rí ọ!

Nígbà tí àwọn méjèjì sì fi ojú rinjú, ọfọ̀ ni Ṣọ̀ún Ogunlọlá lò kí ó tó lè borí Ẹlẹ́mẹ̀ṣọ̀ tí ó ti ń pa àwọn ará ìlú ṣeré. A fẹ́ kí ó di mímọ̀ pé kì í ṣe gbogbo ẹni tí ó ń lo ọfọ̀ ni ọfọ̀ máa ń jẹ́ fún. Ibi tí ẹni kan mọ ìlò ọfọ̀ dé ni ti ẹlòmíì ti bẹ̀rẹ̀. Kì í wá ṣe inú fíìmù ajẹmọ́-ẹ̀pîìkì nìkan ni a ti máa ń lo ọfọ̀ nínú àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá. A rí ìlò rẹ̀ nínú àwọn fíìmù àìjẹmọ́-ẹ̀pîìkì, pàápàpá tí wọ́n bá ṣe ìwádìí ní ọnà ìbílẹ̀ tàbí ní ìran tí wọ́n ti fi àwọn àjẹ́ hàn.

Ìlò èpè nínú àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá gbòòrò díẹ̀ ju ìlò ọfọ̀. Èpè ni ìdàkejì ìre. Èpè jẹ́ ìsọ tí a lè fi fa ibi tàbí àjálù sí orí ẹnìkan, àgbájọ ènìyàn, ìlú tàbí ìran ènìyàn, Olúmúyìwá (ó ń bọ̀ lọ́nà). A ti sọ ṣáájú pé wọ́n lè lo ọfọ̀ láti dojú ìjà kọ ọtá tàbí kí á lò ó láti gba ara ẹni sílẹ̀. Ẹni tí ó ṣe

ohun tí èèyàn ò fẹ́ ni wọ́n máa ń ṣẹ́ èpè fún. Èpè ò ṣe é ṣẹ́ láti gba ara ẹni sílẹ̀. Ó fẹ́rẹ̀ má sí fíìmù àgbéléwò Yorùbá kan tí wọn kò ti ṣẹ́ èpè. Inú fíìmù ajẹmọ́-àwàdà ni a ṣe àkíyèsí pé ìlò èpè ti pọ̀ jù. Àwọn òṣèré Yorùbá kò tilẹ́ rí èpè gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó lè ṣe ènìyàn ní ibi. Wọ́n ti sọ èpè di nǹkan àpára. Ohun tí Olúmúyìwá (2016:299) rí rè é tí ó fi pe èpè nínú fíìmù àgbéléwò Yorùbá ní *vulgar epithet*- ọ̀rọ̀ àlùfàǹṣà/ ìsọkúsọ. Àpẹẹrẹ èpè bẹ́ẹ̀ ni:

> 'Mo gbé, kò ní dáa fún ọ'
> 'Ọlọ́run ni yóò kọ̀ ọ́.'
> 'Ayé mi bàjẹ́, Dayọ̀, ò ń *toast*'
> 'Kò ní yẹ ọ́, orí rẹ burú'

Ṣùgbọ́n bí ọ̀rọ̀ bá dun ni dé góńgó tó sì gba omijé lójú ẹni, Yorùbá máa ń fi èpè jà. Irú èpè bẹ́ẹ̀ lè má ṣiṣẹ́ lójú ẹsẹ̀ bí ti ọfọ̀. Èpè bẹ́ẹ̀ máa ń dúró di ọjọ́ iwájú kí ó tó jà ni. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń sọ pé 'èpè máa ń rò kí ó tó jà.' A rí ìlò èpè bẹ́ẹ̀ nínú fíìmù *Àfọ̀njá*. Aláàfin Aólẹ̀ fi ìkanra ṣẹ́ èpè fún ìran Àfọ̀njá kí ó tó ta ọfà àṣẹ sí orígun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ayé. Ó ní:

> Wọ́n ní a kì í rórí adé fín. A kì í fi ìjòyè ṣẹ̀sín… Àfọ̀njá rí mi fín…Èmi ni ìran tí ẹ ní lóde ayé lónìí.
> Nítorí náà, Àfọ̀njá rí yín fín. Ẹ jẹ́ kí àwọn ọmọ rẹ̀ ó rí i fín, Ẹ jẹ́ káwọn ẹrú rẹ̀ ó rí i fín. Bó bá rán ẹrú rẹ̀ níṣẹ́, kí wọ́n má lè jábọ̀ fún un. Àwọn ẹrú rẹ̀ ni kó máa ṣe aṣáájú àwọn ọmọ rẹ̀…

Bóyá èpè tí Aláàfin Aólẹ̀ ṣẹ́ yìí ló sì ń ja ìran Àfọ̀njá di òní yìí tí àwọn ìran rẹ̀ kò fi jọba ìlú Ìlọrin mọ́, Johnson (1921:200).

Aláàfin Aólẹ̀ ò ní ohun méjì tí ó fi ń bá ọ̀tá rẹ jà nínú fíìmù *Àfọ̀njá* àfi èpè. Nígbà tí ó wòye pé àwọn olóyè òun ń gbàbọ̀dè, ó ti èpè bọ ẹnu, ó ní:

> Ẹni tó ní kí n má fẹ̀dọ̀ lórí òrónró lórí ọba…
> Bí ẹkún bí ẹkún níí ṣegbére
> Bí ọ̀fọ̀ bí ọ̀fọ̀ níí ṣàparò
> Ọ̀rọ̀ ẹkún ò ní tán nílé wọn…
> Àwọn tí yóò kú réderède
> Àwọn tí yóò kú rádaràda
> Àwọn tí ò ní kú síbi aṣọ wọn wà.
> Awọn tí yóò ṣòfò bí omi ẹ̀fọ̀
> Àwọn olórí burúkú tí nǹkan re ò ní ya sọ́dọ̀ wọn…

Réderède, rádaràda tí Aláàfin Aólẹ̀ wí yìí ni ó gbẹ̀yìn àwọn olóyè rẹ̀ àti òun pàápàá.

Bákan náà nínú fíìmù *Èpè Ọjọ́sí*, Agbábíàká, bàbá Bọ́látitó fi Bọ́látitó ṣẹ́ èpè nítorí ó kọ ọ̀rọ̀ si lẹ́nu pé kí ó má lọ sí Èkó. Ó ní:

> Bó bá jẹ́ èmi ni mo bí ọ, o ò ní jèrè bó o
> bá re Èkó. Wọn ó ru òkú ẹ wá bá mi ni.
> Èmi ni mo sọ bẹ́ẹ̀.

Bọ́látitó lọ sí Èkó lóòótọ́, Ìgbà tí ó dé ọ̀hún, ó pàdé ọkùnrin tí wọ́n ti ṣẹ́ èpè lé, ó fi ṣe ọkọ. Lọ́rọ̀ kan, òkú rẹ̀ ni wọ́n gbé wálé wá bá bàbá rẹ̀. Ìbànújẹ́ bá Agbábíàká, ó tún ṣẹ́ èpè fún àwọn tí ó gbé òkú Bọ́látitó wálé pé wọn ò ní dé Èkó. Ìlú Agbábíàká níbẹ̀ ni èpè náà ti ja ọ̀kan nínú àwọn tí ó gbé òkú Bọ́látitó wálé. Ọkọ̀ gbá a, ó sì kú lójú ẹsẹ̀. Jìnnìjìnnì bo àwọn méjì tó kù, wọ́n tẹ̀ ẹ́ pa sọ́dọ̀ Agbábíàká, wọ́n ń bẹ̀ ẹ́. Ìgbà tí kò gbọ́ ẹ̀bẹ̀ ni ẹni tí ó ṣẹ́ èpè náà lójú ẹ̀ bá kò ó lójú pé òun ló

pa ọmọ ara rẹ̀. Ó rán an létí èpè tó ṣẹ́ lé Bọ́látitó nígbà tí ó ń lọ sí Èkó. Ara rọ Agbábíàká wọ̀ọ̀. Nígbà mìíràn, èpè a máa ja odindi ìlú. A rí àpẹẹrẹ rẹ̀ nínú fíìmù *Ṣíjúwadé* níbi tí bàbá ọ̀kan lára àwọn tí ọba Abọ̀rú ní kí wọ́n pa ti fi ìlú náà ṣẹ́ èpè. O ní:

> Ẹni pa igúnnugún kò ní kádún
> Èeyàn tó pàkàlàmàgbò kò ní káṣù mẹ́fà.
> Ẹni pa kátákàtá ò ní pọ́dún mẹ́ta.
> Abọ̀rú, òfò, ìbànújẹ́, ìpọ́njú, àrélù
> ni kó máa dé báa yín títí ọba Abọ̀rú yóò fi wàjà.

Lẹ́yìn èpè yìí ìlú Abọ̀rú ò fara rọ. Omi ìlú di ẹ̀jẹ̀. Ọmọ ènìyàn bá ewúrẹ́ sùn. Awọn olóyè ìlú kọ ẹ̀yìn sí ọba. Ọmọ ìyá méjì ń fi ipá bá ara wọn lò. Àwọn ọ̀dọ́ ìlú ń fò ṣánlẹ̀, wọ́n ń kú ikú òjijì, ikú àìmọ̀dí. Rògbòdìyàn yìí ló fà á tí awọn ọ̀dọ́ ìlú fi kó ara jọ láti fi ẹ̀hónú hàn, Wọ́n já ewé lọ́wọ́ wọ́n sì ń kọrin ọ̀tẹ̀ láti tako ọba Adédàpọ̀ ti ilú Abọ̀rú. Wọ́n ní:

> Àwa ò fẹ́ o,
> Àwa ò gbà.
> Àwa ò fara mọ nílẹ̀ yìí o,
> Ọba Adédàpọ̀, lílọ ní ọ́ọ́ lọ.

Ọ̀tẹ̀ yìí ló mú ọba Adédàpọ̀ ṣíjú wo adé. Bí ọba bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, ó gbọ́dọ̀ wàjà. Orin ọ̀tẹ̀ àti ìfẹ̀hónú han tí àwọn ọ̀dọ́ ìlú kọ yìí jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà tí àwọn aláìlágbára fi ń jagun ẹnu látijọ́ àti lóde òní bí wọ́n bá fẹ́ kọ ìrẹ́jẹ, ìtẹ̀mọ́lẹ̀ àti ìfẹ̀tọ́-ẹni-dunni. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní 'bí a bá dákẹ́, tara ẹni a bá ni dákẹ́.' Ẹnu lọ́ọ̀lọ́ọ́ yìí ni àwọn òṣìṣẹ́-fẹ̀yìntì ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ya lu òpópónà tí ó lọ sí ọ́fíìsì gómìnà ìpínlẹ̀ náà lórí àìsan owó pẹ́ńṣàn fún

wọn. Àwọn tó já ewé já ewé. Àwọn tó yọ igi nínú wọn yọ igi. Oríṣiríṣi pátákó àti tákàdá ńlá ni wọn kọ èébú sí. Wọ́n mórin bọnu, wọ́n ní:

Ojú olè rè é... Olè!
Ojú olè rè é... Olè!!
Òfò ni óò ṣe,
Ẹni bá tẹ̀lé Ràúfù,
Òfò ni óò ṣe...

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èpè ni wọ́n fi orin yìí ṣẹ́, àwọn ọlọ́pàá tó gbé ìbọn dání níbi ìṣẹ́lẹ̀ náà kàn ń wò wọn ni láìṣe ohunkóhun. Ohun tí a rí mú jáde níbi ìṣẹ̀lẹ̀ náà ni pé àwọn ará ìlú sì ń fi ẹnu bá àwọn olórí ìjọba jagun láwùjọ ìjọba tiwantiwa lónìí. Kì í wá ṣe àwọn òṣìṣẹ́-fẹ̀yìntì nìkan ni ó ǹ máa kọrin ọ̀tẹ̀ bí èyí tí a tọ́ka sí lókè yìí láti jagun ẹnu láwùjọ òde-òní. Awọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn orogún lọ́ọ̀dẹ̀ ọkọ kò gbẹ́yìn nínú fí fi irú orin báyìí jagun ẹnu. Àpẹẹrẹ irú orin yìí ni a mú nínú fíìmù *Pélé Modina*.

Aṣọ kí lẹ ró
Tẹ́ ẹ wú kalẹ̀, tẹ́ẹ́ wú gágá'

Èsì:

Ọjọ́ ọdún lẹ̀sín ń yọ
Ọjọ́ ọdún lẹ̀sín ń yọ
Ìyàwó ọ̀bùn aláìníṣẹ́ lápá
ọjọ́ ọdún lẹ̀sín ń yọ.

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní 'ẹnu níí pa ni, ẹnu níí la ni.' Ẹ̀dá tí kò bá kíyèsí ara nípa ohun tí ó ń sọ bí Bánkárere nínú fíìmù *Bánkárere Asọ̀rọ̀sọbótò* lè bá ara rẹ̀ nínú ẹ̀wọ̀n. Yorùbá ní

'bójú bá rí ẹnu a dákẹ́.' Wọ́n sì tún ní 'Àrîìgbọdọ̀wí baálé ilé ṣu sí apẹ.' Bí i ti Bánkárere kọ́. Ìgbàgbọ́ rẹ̀ ni pé ọ̀rọ̀ kì í tóbí ká fi ọ̀bẹ bù ú, ẹnu náà ni a ó fi sọ ọ́. Ó ní bójú bá rí dandan ni kí ẹnu ó sọ. Ó tiẹ̀ máa ń dáṣà pé 'ọ̀rọ̀ kan ò lè fa àwa lẹ́nu ya mọ́ àfi bí yóò bá fà wá láṣọ ya. Bó bá sì fà wá láṣọ ya, a óò ran.' Bánkárere fi ọ̀rọ̀ ba ìlú jẹ́, ó fi da ilé rú, ó tú àṣírí ìwà ìbàjẹ́ Kábíèsí nídìí ayò. O fi ọ̀rọ̀ náà kó bá ara rẹ̀, ó fi kó bá òbí. Ó sá kúrò nílùú nígbà tí ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ dìde ogun sí i. Ó dé ilú Ìbàdàn ó tún fi ẹnu kọ. Wọ́n jù ú sínú túbú. Àsìkò náà ló tó kábàámọ̀ ìwà rẹ̀. Ó ní:

> Ẹnu olúbọ́bọ́tiribọ́ baba ẹbọ.
> Ẹnu táa bọ bọ bọ tá ò le bọ tán,
> Àfi ọjọ́ tí ikú bá mú ni lọ.
> Ẹnu níí pa ni, ẹnu níí la ni.
> Ẹnu níí mú ni lájẹ̀ẹ́.
> Ẹnu sì níí sọ ni lórúkọ rere.
> Orí ẹni kó kó ni yọ lọ́wọ́ ẹnu…

Lẹ́yìn-ò-rẹ́yìn, wọ́n tún le é kúrò nílùú Ìbàdàn. Ẹyin lohùn, bó bá ti balẹ̀, kò ṣé kó. Ìwé Òwe 18:21 nínú Bíbélì ní "ikú àti ìyè ń bẹ nípa ahọ́n, àwọn tí ó ń lò ó yóò jèrè rẹ̀". Bákan náà ni Ọmọ Ìlọ̀rí tí ó jẹ́ olorì ọba Májẹ́ógbé nínú fíìmù *Baṣọ̀run Gáà* fi ẹnu ẹ̀ pa bàbá rẹ̀ lórí àìkóra-ẹni-níjanu. Ó ń bá ọba Májẹ́ógbé dápàárá, ó ní:

> Olúwa mi, bí mo ti ń wò yín, àṣé bí ẹ ti mọ jáńtíọ́ nìyí tí gbogbo ayé sì wá ń bẹ̀rù yín... Kí ni wọ́n ń bẹ̀rù lára yín gan-an? Olúwa mi ẹ ṣe nǹkan sára ni..

Ọba Májẹ́ógbé ò ba sọ nǹkan kan. Ó ní kí wọ́n lọ gbé orí bàbá rẹ̀ sínú igbá wá fún òun. Májẹ́ógbé ní kí wọ́n gbé igbá náà fún olorì. Olorì ṣí igbá, ó bú sẹ́kun. Ikú Ìlọ̀rí bàbá olorì yìí kún ara ẹsùn tí Baṣọ̀run Gáà fi gbẹ̀mí Májẹ́ógbé. Ìyá Núré nínú fíìmù *Túlétúlé* ní tirẹ̀ máa ń fi ẹnu rẹ̀ da àdúgbò rú ni. Ó fi ẹnu da ààrín lọ́kọ-láya rú, ó sán orí ọ̀rẹ́ mẹ́ta pọ̀ nípa irọ́ pípa. Ó dá aáwọ̀ sílẹ̀ láàrín bàbá-onílé rẹ̀ àti ìyàwó rẹ̀. Òun gan-an mọ̀ pé ẹnu òun ò dáa. Ó bi Núré ọmọ rẹ̀ léèrè lẹ́yìn tí ó ti da ọ̀rọ̀ sílẹ̀ tán fún àwọn kan, ó ní:

Ìyá Núré: Núré, ṣé mi ò sọ̀rọ̀ jù ṣá?

Núré: Ẹ̀yin wo?, ẹ̀yin tẹ́ ẹ rébọ́ tán!

Ìyá Núré: Ó dáa, dákun bá mi sáré lé wọn kí n lè rìfáàsì (reverse) rẹ̀ àbí báwo?

Ibi ọ̀rọ̀ àsọjù rẹ̀ yìí ni ó fi sọ̀rọ̀ àkọ́bí ọmọ rẹ̀ lé àwọn tó ṣekú pa á lọ́wọ́. Ìgbà yìí ló tó ki ika àbámọ̀ bọ ẹnu. Ẹlẹ́nu mímú ni tọkọtaya Jẹjẹlóyẹ. Èpè àti èébú ni wọ́n fi ń wẹ ara wọn lójoojúmọ́ nínú fíìmù *Jẹ́jẹ́lóyẹ*. Bí ìyàwó bá yọ èébú lára ọkọ tán, yóò tún fi èpè kan tì í. Ọkọ náà kì í jẹ́ kí ó balẹ̀ kí ó tó fún un lésì. Bí ó ti ń bu ìyàwó rẹ̀ ni yóò máa rán an sílé. Ìyàwó á tún dá èsì padà fún un. Ó ní 'èmi kì í ṣe ọmọ lọ sílé lọ gbèsì wá.' Ọ̀nà mìíràn tí ẹnu fi ń pa ènìyàn ni kí ó sọ̀rọ̀ òdì sí ara rẹ̀. Ènìyàn tún lè sọ̀rọ̀ òdì sí ẹlòmìíràn. Nínú fíìmù *Nimí*, Túnmiṣe kò sọ̀rọ̀ sí ìyàwó rẹ̀ nínú ilé mọ́ nítorí kò sí ohun tí ó sọ fún un tí ó yọrí sí rere. Àlùfáà bá gbà á ní ìmọ̀ràn kí ó kọ́ bí wọ́n ti ń dákẹ́. Túnmiṣe sá kúrò láìsọ fún Nimí ìyàwó rẹ̀.

Nimí kẹ́rù kúrò nílé kí Túnmiṣe tó padà dé. Ìgbà tí wọ́n ń dá Túnmiṣe lẹ́bi pé ó ṣe ohun tí ò tọ́, ó ní:

> Nimí tí ẹ̀ ń wò yìí ló ba ayé mi jẹ́. Àìmoye ọ̀rọ̀ òdì ló sọ sínú ayé mi tó ti ṣẹ....

Nígbà mìíràn, ìbúra tún lè ṣe okùnfà kí ènìyàn sọ̀rọ̀ òdì sí ara rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, a rí àwọn méjì tí wọ́n ṣe ìbúra fún ara nínú fíìmù *Ibú*. Àwọn méjèèjì búra pé:

> 'bí mo bá dà ọ́, kí n má jèrè.'

Nítorí ìdí tí ó kọjá òye ẹ̀dá, àwọn méjèèjì dalẹ̀ ara wọn láì mọ̀ọ́mọ̀. Ọ̀rọ̀ òdì tí wọ́n sọ sí ara wọn nípasẹ̀ ìbúra sì ṣẹ. Yàtọ̀ sí sísọ ọ̀rọ̀ òdì sí ara ẹni, ẹnu dídán àti ẹnu dídùn tún lè fa ogun sínú ayé ẹni. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní 'ẹnu dùn-ún ròfọ́, agada ọwọ́ ṣé é ṣán oko'. Nínú fíìmù *Alákadá* àti *Bùgá*, ẹnu ni àwọn olú-ẹ̀dá ìtàn inú fíìmù méjèèjì fi ya ẹja sí ọbẹ̀ tóbẹ́ẹ̀ tí aláàánú fi jìnnà sí wọn. Àbámọ̀ ló gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ wọn.

Bí ẹnu ṣe ń pa ènìyàn náà ni ènìyàn lè fi ẹnu gba ara rẹ̀ là. Ẹnu yìí ni ọba Ìwéré fi gba ara rẹ̀ sílẹ̀ nígbà tí àwọn ọmọ ogun Àfọ̀njá tí Aláàfin Aólẹ̀ rán wọ̀lú mu un. Ó kọjú sí wọn, ó ní:

> Kí ni a ṣe ní Ìwéré-ilé tí ẹ fi sígun wáà bá wa ní Ìwéré ilé Ọba yín ò mọ̀tàn ni àbí kò fi ọ̀rọ̀ náà lọ Kakaǹfò… Kò mọ̀ pé Ìwéré-ilé ni ìlú ìyá ọba Abíọ́dún? Ọba Àjàgbó sì ti ṣépè wí pé Ààrẹ ọ̀nà-Kakanfò tó bá ṣígun wọ̀lú òun, Ààrẹ ọ̀nà-Kakaǹfò náà kò ní fọwọ́ rọrí kú… ọba yòówù tó bá fi irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ rán Ààrẹ́ ọ̀nà Kakaǹfò, òun náà ti forí gbèpè.

Ọba Ìwéré ṣe àtúnwí ohun tí ó sọ yìí níwájú Àfọ̀njá, Àfọ̀njá jọ̀wọ́ ẹ̀ sílẹ̀. Yàtọ̀ sí pé ọba Ìwéré-ilé fi ẹnu gba ara rẹ̀ sílẹ̀, a tún rí i nínú ohun tí ọba yìí sọ bí èpè ṣe máa ń jà.
Yorùbá mọ̀ràn wọ́n ní 'ẹni tí yóò sọ iró di òótọ́ yóò jagun ẹnu.' Àwa náà wá fi kun pé ẹni tí yóò sọ òótọ́ di irọ́, yóò jagun ẹnu. Bí igi bá ré lu igi, tòkè rẹ̀ ni a kọ́kọ́ máa gbé. Oríṣiríṣi ọ̀nà ni ènìyàn lè gbà láti sọ òótọ́ di irọ́. Lára ọ̀nà bẹ́ẹ̀ ni ìbanilórúkọjẹ́, àhesọ, ẹ̀tàn, ìsọ̀rọ̀-ẹnilẹ́yìn-láìdáa àti ìfẹ̀sùn-èké-kanni. Gbogbo ọ̀na tí a là sílẹ̀ yìí ni àwọn awo ìkà lò láti ṣí Àbẹ̀ní Alágbo-òru kúrò nílùú nínú fíìmù *Àbẹ̀ní Alágbo-òru*. Àwọn awo ìkà wọ̀nyí tan ọba àti àwọn ènìyàn ìlú jẹ nípa píparọ́ mọ́ Àbẹ̀ní Alágbo-òru. Wọ́n ba Àbẹ̀ní lórúkọ jẹ. Ọba ju Àbẹ̀ní sí ọgbà ẹ̀wọ̀n lórí ẹ̀ṣẹ̀ àìmọ̀dí. Oríṣiríṣi ahesọ ni àwọn ará ìlú ń sọ nípa rẹ̀. Wọ́n fi ẹnu lé Àbẹ̀ní Alágbo-òru kúrò nílùú tán, àìrójú àìráyè àti àjàkálẹ̀ àrùn gba ìlú kan. Àsìkò yìí ni ọba ṣẹ̀ṣẹ̀ mọ̀ pé àwọn awo èké náà tan òun jẹ ni.

Nínú fíìmù *Ti Olúwa ni ilẹ̀* ọ̀gbẹ́ni Sànyà àti lọ́yà Kọ́lá Ajíbádé ta ilẹ̀ òòṣà, ilẹ̀ ìlú. Wọ́n fi ọgbọ́n mú Ọ̀tún ìlú mọ́ra láìsọ òòtọ́ iye ti wọ́n talẹ̀ fun un. Wọ́n ta ilẹ̀ ilú tán wọ́n tún gbé ìlú lọ sílé ẹjọ́. Agbẹjọ́rò Sànyà àti Kọ́lá Ajíbádé gbo ọba Joseph Abọ́ládé Agbálátirá Òkè gìrìgìrì pẹ̀lú ìtàn èké. Ọ̀tún ìlú tí wọ́n pè kí ó wá jẹ́rìí, jẹ́rìí èké ta ko ìlú. Ó ní òòtọ́ ni ìtàn tí Sànyà sọ pé Òkèládéọ̀kín ló fún bàbá Eléjìogbè nílẹ̀ tí wọ́n tà. Àti pé bàbá Eléjìogbè yìí ló bí ìyá òòṣà tí ó ń bọ òòṣà lórí ilẹ̀ náà. Ó parí àlàyé rẹ̀ pé ìyá òòṣà yìí ló bí bàbá-bàbá Sànyà.

Lọ́rọ̀ kan, wọ́n jagun ẹnu, adájọ́ dá wọn láre. Sànyà, Kọ́lá Ajíbádé àti agbẹjọ́rò wọn ń ṣe ajọyọ nílé ọtí lórí ìdáláre tí wọ́n rí gbà nílé ẹjọ́. Ọ̀tún ìlú bá wọn níbẹ̀, ó dápàárá, ó ní: 'Ti Olúwa ni ilẹ̀ àti awọn tó bá mọ̀tàn rẹ̀.' Lóòótọ́, wọ́n jagun ẹnu wọ́n ṣẹ́gun nípa sísọ irọ́ di òòtọ́ lójú adájọ́. Ohun tó wà lẹ́yìn ẹ̀fà ju eje lọ. Ikú ni Sànyà àti Kọ́lá Ajíbádé fi ṣe ìfà jẹ nígbà tí ogun ẹnu tí wọ́n ti kọ́kọ́ borí tẹ́lẹ̀ dojú kọ wọ́n. Olè wọlé, ó gba owó lọ́wọ́ agbẹjọ́rò wọn. Ọ̀tún ní tirẹ̀ wọnú ìdààmú.

## Agbálọgbábọ̀

Àyẹ̀wò ogun ẹnu nínú àṣàyàn fíìmù àgbéléwò Yorùbá ni a ṣe nínú iṣẹ́ yìí. A ti sọ ohun ti ogun ẹnu jẹ́. A sì mẹ́nu ba àwọn ohun tí ó ń dá ogun sílẹ̀ láwùjọ. Lẹ́yìn náà ni a wá ṣe àyẹ̀wò rẹ̀ nínú àṣàyàn fíìmù àgbéléwò Yorùbá. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí a rí òye oríṣiríṣi nǹkan tí a fi ń jagun ẹnu. Lára àwọn nǹkan bẹ́ẹ̀ ni ọfọ̀, èpè àti orin. Bákan náà ni iṣẹ́ yìí jẹ́ kí a mọ àwọn ọ̀nà tí ogun ẹnu lè gbà ja ẹ̀dá. K ì í wá ṣe gbogbo ìgbà lẹnu máa ń pa ni. Yorùbá ní 'bí a bá dákẹ́, tara ẹni lè bá ni dákẹ́.' Ènìyàn lè fi ẹnu gba ara rẹ̀ sílẹ̀. Èyí ni àwọn Yorùbá rò tí wọ́n fi ní; 'Àìlè sọ̀rọ̀ ni ipilẹ̀ orí burúkú' àti pé 'ẹnu ara ẹni la fi ń kọ mé jẹ

## Ìtọ̀sẹ̀-ọ̀rọ̀

1. Àwọn òwe wọ̀nyí ni a mú láti inú Ajíbọ́lá (1947), Badà (1970), Ọládàpọ̀ (1996) àti Ṣótúndé (2009).

## Ìwé Ìtọ́kasí

Abimbọ́lá, W. (1977). Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún. Ìbàdàn University press.

Adébáyọ̀, F. (1965). *Ogun Awítẹ́lẹ̀.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Adélékè, D.A. (1995). Audience reception of Yorùbá films: Ìbàdàn as case study. Unpublished Ph.D. Thesis, University of Ibadan.

Adéniji, D.A.A. (1987). *Ogun ní ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn: Longman Nigeria Limited.

Adeoyè, C.L. (1979). *Àṣà àti ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Adétóyè, A.O. (2009). Ìmọ̀ Ìjinlẹ̀ Èrò Yorùbá Lórí Ogun Ẹnu. M.A. Thesis, Ìlọrin: University of Ìlọrin.

Adétóyè, A.O. (2015). Ipa àti ipo Ogun Ẹnu Nínú Eré-Onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* nínú *Ède, Àṣà àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá: Ìtan-ò-ní-gbàgbé-yín: Olóyè Díípọ̀ Gbénró àti Alagbà Fúnṣọ́ Fátókún*. Adéṣuyan, M.M., Raji, R.A. àti Òjó, I. (Àwọn Olóòtú) Ibadan: Master print Publishers.o.i 412-419.

Ajíbọ́lá, J.O. (1947). *Òwe Yorùbá*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Àlàmú, O.O. (2010). *Aesthestics of Yorùbá film*. Research Institute for World Languages. Osaka University, Japan.

Badà, S.O. (1970). *Òwe Yorùbá àti Ìṣẹ̀dálẹ̀ wọn*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Bible Society of Nigeria (2006). *Bíbélì Mímọ́ Atọ́ka.* Lagos: BSN, Àpápá.

Fábùnmi. M.A. (1972). *Ayájọ́ Ijìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifẹ̀*. Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press.

Husseini, S. (2010). *Moviedom...Nollywood Narratives Clips on the Pioneers*. All Media International Ltd/African Film Academy.

Ibítóyè, E.O. (2012). The Enduring Impact of the 1804 Fulani Jihad on Igbomina Society. *Journal of African Studies & Development*, Vol 4:4 o.i.105-113.

Jeyifo, B. (1984). *The Yorùbá Popular Traveling Theatre of Nigeria*. Lagos: Department of Culture, Federal Ministry of Social Development, Youth, Sports and Culture.

Johnson, S. (1921). *The History of Yorùbá*. Lagos: C.S.S. Bookshop.

Mgbejume, O. (2006). Movie stories: The surgical cure for emotional problems. *Beyond the Screen. A Journal of the National Film Institute*, Vol 1:1 o.i. 36-42.

Ọládàpọ̀, T. (1996). *Ẹgbẹ̀ta Òwe 'B'*. Ìbàdàn: Ọlátúbọ̀sún Records Company.

Ọlátunji, O.O. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn: University Press Limited.

Olúmúyìwá, T. (2016). The Linguistics Appraisal of Foul Language in selected Yorùbá Video films. *Humanities & Social Sciences, Journal of Siberial Federal University*, 9(2). O.i. 294-309.

Olúmúyìwá, T. & Aládésanmí, A.O. (2017). Semantic Implications of Preverbal Adverbs in Adúrà and Èpè Among the Yorùbá. *Inquiry in African Languages and Literatures*. No. 10 o.i 131-138.

Olúmúyìwá, T. (ó ń bọ̀ lọ́nà) *Ìlò Èébú àti Èpè nínú àwọn Àṣàyàn fíìmù Àgbéléwò Yorùbá*. Àkúrẹ́: Montem Paperbacks

Ọpẹfẹyitimi, A. (2010). *Ìtúpalẹ̀ Èpè*. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press.

Salami, A. Àti Ọlawalé, B. (2013). Ibadan slaves and Ibadan wars in Pre-colonial South western Nigeria, 1835-1893. *IOSR Journal of Humanites and Social Science* Vol. 7 issue 3, o.i 32-38.

Ṣótúndé, F.I. (2009). *Yorùbá Proverbs and Philosophy*. Abẹ́òkúta: Damsan Nig. Company.

Timothy-Asobele, S.J. (2003). *Yorùbá Cinema of Nigeria*. Lagos: Upper Standard Publications.

## Àwọn Fíìmù tí a yẹ̀wò

*Ààrẹ Apàṣẹ*. Arinọla Adams, (2012). Olasco Films Nigeria Limited.

*Àbẹ̀ní Alágbo-òru*. Ibikunle Kabir Adé, (2012). Zainab Ventures Limited.

*Àfọ̀njá*. Bíọ́dún Ìbítọ́lá, (2001). Remdel Optimum Communications Limited.

*Alákadá*. Toyin Aimakhu, (2009) Epsalum Movie Production Ltd.

*Bánkárere*. T.A.A. Ládélé, (2012). Glamour Films & Records Limited.

*Báṣọ̀run Gáà*. Afan, (2003). Remdel Optimum Communications Limited.

*Bùgá*. Fẹmi Adébáyọ̀, (2013). Epsalum Productions.

*Èpè Ọjọ́sí*. Bùsáyọ̀ Onífádé, (2013). Highway Video Mart.

*Fọ́pomọ́yọ̀.* Jimoh Aliu, Goldlink Productions.

*Ibú*. Jámiu Fasasí, (2012). Afasco Global Pictures Limited.

*Jẹ́jẹ́lóyẹ.* Toyin Aimakhu, (2012). Tenten Pictures limited.

*Nimí*. Bola Mojeed, (2016). Highway Video Mart.

*Ogun Àgbẹ́kọ̀yà*. Lérè Paímọ́, (2012). Diamond Pictures.

*Ògbórí Ẹlẹ́mẹ̀ṣọ́*, Lérè Paímọ́. Afelele &Brothers Nigeria Limited.

*Pélé Mọ̀dínà.* Ọláníyì Àfọ́njá, (2013), Adekaz Productions Ltd.

*Ṣíjúwadé*. Fathia Balógun, (2017). Corporate Pictures.

*Ti Olúwa ni ilẹ̀*. Túndé Kèlání, (1995). Mainframe Production.

*Túlétúlé*. Káyọ̀dé Adébáyọ̀, (2017). Easyway Pictures Ltd.